## IDAGBASOKE ONIGBAGBỌ́ NINU OORE-ỌFẸ

**2 Peteru 1:1-21**

**ẸKỌ 454 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: Ẹ mã dagba ninu oore-ọfẹ ati ninu imọ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi" (2 Peteru 3:18).**

**I Didé Ipò Igbesi-ayé Iwa-bi-Ọlọrun**

1 Ọrọ ikini Peteru ni ibẹrẹ jẹ ipolowo koko pataki ti i ṣe didagba ninu oore-ọfẹ, 2 Peteru 1:1, 2; 3:18

2 Nipa agbara Kristi ni a le ri awọn oore-ọfẹ iwa ayé Kristi gba, 2 Peteru 1:3, 4; Filippi 4:13

3 Ẹkọ Ọlọrun nipa didagba jẹ nipa fifi oore-ọfẹ kún oore-ọfẹ, 2 Peteru 1:5-8; Efesu 4:13

**II Anfaani Pupọ Wà lati wọ Ọrun**

1 Aisinmi ṣe pataki lati sọ ipe ati yiyàn eniyan di didaju, 2 Peteru 1:9, 10; Heberu 11:6; 2 Tẹssalonika 1:11

2 Anfaani pupọ ni a o fún ẹni ti o ba ṣe aisinmi lati wọ ile, 2 Peteru 1:11; Daniẹli 12:3

3 Peteru, ẹni ti o mọ pe opin n sun mọ tosi fun oun, gba awọn Onigbagbọ́ niyanju lati maa ṣe aisinmi, 2 Peteru 1:12-15; Johannu 21:18, 19

**III Peteru bu Iyin fun Ọrọ Ọlọrun**

1 Peteru jẹri si ohun ti o ṣẹlẹ lori Oke Ipalarada, 2 Peteru 1:16-18; Matteu 16:28; 17:1-8

2 A ri ifidimulẹ asọtẹlẹ ti a ti sọ nigba laelae nipa Jesu ninu iṣẹlẹ lori Oke naa, 2 Peteru 1:19; Deuteronomi 18:15

3 Asọtẹlẹ ti ipasẹ imisi Ẹmi Mimọ́ wá, kò si si itumọ ikọkọ fun un, 2 Peteru 1:20, 21; 2 Timoteu 3:16, 17; Johannu 16:13.

### ALAYE

**Iwa Mimọ́**

Koko kan nipa eyi ti a ti kọ ọpọlọpọ akọsilẹ ti a si tẹnumọ lọpọlọpọ ni a ri ninu gbogbo Episteli ti a kà sẹyin, ati ninu Ihinrere pẹlu: ọrọ IWA MIMỌ́ "li aisi eyini kò si ẹniti yio ri Oluwa". Paulu, Jakọbu ati Peteru ya ọpọlọpọ akoko sọtọ, wọn si ṣaapọn lati kọ́ awọn Onigbagbọ́ nipa ọna ti a le gba sọ iwa mimọ́ di pipé ninu igbesi-ayé wọn.

Ninu awọn ẹsẹ Ọrọ Mimọ́ nihin yii Peteru Apọsteli tun tẹ̀ siwaju pẹlu "Didagba ninu Ore-ọfẹ́". A kò le rin jinna ninu Iwe Mimọ́ ki a to ri i pe bi Onigbagbọ yoo ba ṣe aṣeyọri nipa ti ẹmi, o ni lati ṣe aisinmi lati wá awọn oore-ọfẹ ti o fara hàn ninu iwa ayé Kristi. Nipa bayii ni a o tubọ maa de giga Rẹ̀ ti a o si maa dagba soke ninu oore-ọfẹ Rẹ̀. Ẹni ti o n lo ohun-elo orin ni lati lo akoko pupọ ki o si ṣe aapọn pupọ lori ẹkọ rẹ̀ ki o to le di ogbogi ninu lilo ohun-elo orin naa. Bakan naa ni Onigbagbọ́ ni lati ṣe aapọn lati di pipé ninu iwa-mimọ́ bi o ba fẹ di Onigbagbọ́ rere, tabi ti o ba fẹ dabi Kristi.

**Igbagbọ́ ti o Ṣe Iyebiye**

Ori kin-in-ni Iwe Peteru keji bẹrẹ pẹlu ikini "si awọn ti o ti gbà irú iyebiye igbagbọ́ kanna pẹlu wa, ninu ododo Ọlọrun wa ati ti Jesu Kristi Olugbala". Ni ede Griki a ni lati pe orukọ Kristi mọ ti Ọlọrun bayii ki o le yanju. Ni ọna kan naa, nigba ti Jesu n sọrọ fun Tọmasi ninu Johannu 20:29, O bukun awọn ti ko ri I, nigba ti o wi pe, "Alabukun-fun li awọn ti kò ri, ti nwọn si gbagbọ́". Paulu Apọsteli sọ fun wa ninu Heberu 11:6; "Ṣugbọn li aisi igbagbọ́ ko ṣe iṣe lati wù u; nitori ẹniti o ba ntọ̀ Ọlọrun wá kò le ṣai gbagbọ́ pe o mbẹ, ati pe on ni olusẹsan fun awọn ti o fi ara balẹ wá a". O ha

jẹ ohun iyanu nigba naa nigba ti ẹni ti kọ akọsilẹ yii pe a ni "iyebiye igbagbọ́?" Iyebiye igbagbọ́ yii jẹ nipasẹ ododo Ọlọrun ti O fi fun ẹni ti o gbagbọ́.

**Idagba ninu Oore-Ọfẹ**

Ifẹ inu Peteru fun pipọ si i ninu oore-ọfẹ ninu eyi ti ẹni ti o gbagbọ n gbé ati alaafia (eso oore-ọfẹ) jẹ ọ̀kan naa pẹlu ọrọ iyanju ikẹyin ti o sọ nipa idagbasoke ninu ori ti o kẹyin Episteli rẹ̀. A sọ nipa pipọ si i yii gẹgẹ bi ibisi nipa imọ Ọlọrun, ati ti Jesu Oluwa wa. Imọ yii jẹ́ nipa ẹkọ ati nipa iriri. Eyi wà ninu ipilẹ gbogbo ẹsin tootọ. Idagbasoke Onigbagbọ ninu oore-ọfẹ duro lori ibisi ninu imọ Ọrọ Ọlọrun ati igbọran si Ọrọ Ọlọrun. (Ka Deuteronomi 8:3 ati Owe 9:10).

Ọrọ nì, "Bi agbara rẹ̀ bi Ọlọrun ti fun wa li ohun gbogbo ti iṣe ti iye ati ti iwa bi-Ọlọrun" fi ẹsẹ mulẹ o si jẹ akopọ gbogbo eto igbala Ọlọrun lati idalare titi lọ de iṣelogo. Eyi paapaa n sọ nipa, iwa mimọ́ ti inu ati ti ode ara ni ayé isisiyii, lilọ siwaju ati ibisi igbesi-ayé nipa ti ẹmi. "Nipa imọ" ti a sọ yii ki i ṣe ohun ti o ni ilana isin aṣiiri kan ninu tabi afiyesi eto ohun asán kan, ṣugbọn igbọran si ifẹ Ọlọrun gẹgẹ bi o ti fi hàn ninu Ọrọ Rẹ̀ (Romu 10:17). "Ogo" n tọka si ogo Iwa Ọlọrun, "Ọlanla" si n tọka si titayọ ati pipé Rẹ̀. Nipasẹ gbogbo ẹkun ẹda Rẹ̀ ni O pe wa sinu awọn ibukun ti o wà ninu Ihinrere.

**Iwà Ọlọrun**

A maa n sọ bayii pe ninu ipe Ọlọrun ni agbára iranlọwọ Rẹ̀ wa. Ipe Rẹ̀ ki i ṣe alai ni awọn ileri ti o tobi ju lọ ti o si ṣe iyebiye ju lọ ninu. Wọn jẹ eyi ti a ko le diyele, wọn si ṣe iyebiye (1 Peteru 1;18, 19). Awọn ileri wọnyii ki i ṣe ti awọn eniyan mimọ́ ti igba Majẹmu Laelae nikan, ṣugbọn wọn jẹ ileri Ihinrere ti o bá gbogbo akoko mu, fun akoko yii, ti o n ṣẹlẹ lojoojumọ ninu igbesi-ayé ẹni ti o gbagbọ tootọ, ti o jẹ ki o ṣe e ṣe fun un lati jé alabapin ninu ẹda ti Ọlọrun, nipa igbọran ati nipa diduro ninu Ọrọ Rẹ̀ (Johannu 8:31). Ẹkọ eke kan wà ti o wi pe gbogbo wa ni Ọlọrun n gbé inu rẹ̀, tabi pe gbogbo wa jẹ́ Ọlọrun ni apa kan, ati pe ohun ti a ni lati ṣe ṣa ni ki a jẹ ki iwa Ọlọrun ti o wà ninu wa jẹ yọ jade. Ori iwe yii n kọ́ wa pe bi a ba ti n gba imọ Ọlọrun ati ileri Rẹ̀ sinu ayé wa ni a le di alabapin ninu ẹda ti Ọlọrun. Kiki nipa kikan ara tabi ogologbo "ọkunrin ni" mọ́ agbelebu (Romu 6:6), nipa jijọwọ ọna ti wa ati ero ti wa lọwọ, nikan ṣoṣo ni a fi le ni ireti pe ẹda Ọlọrun le maa gbé inu wa. Nigba ti a ba mọ ipese ti Ọlọrun ti ṣe silẹ fun wa, nigba naa ni a to le mọ bi ọrọ̀ wa ti pọ to! (2 Kọrinti 8:9). A maa n yọ kuro ninu ibajẹ ti ó wà ninu ayé ti o ti ipasẹ ifẹkufẹ wá nipa itoye Ẹjẹ iyebiye Jesu. A maa mu ifẹkufẹ ti i maa lepa ayé yii kuro a si maa mu ki a fi tọkantọkan fẹran Ọlọrun. Ipe Ọlọrun jẹ ipe si iwa aileeri ati iwa mimọ́.

**Anikun Oore-Ọfẹ**

Leke ati rekọja ohun wọnni ti a ti sọ ti Ọlọrun ṣe ti o si ti sọ di pupọ fun wa, ẹ jẹ ki a ṣe ipa ti wa nipa fifi kún igbagbọ wa, tabi nipa nini idaniloju ohun ti a kò ri. Itumọ "ẹ mã ṣe aisimi gbogbo" ni pe Ọlọrun ni o n ṣe iṣẹ naa, sibẹ eyi ko le ri bẹ afi bi a ba n ṣe aisinmi lati ṣe ipa ti wa ni titẹle Ọrọ Ọlọrun. Ninu oriṣiriṣi oore-ọfẹ Onigbagbọ́ wọnyii, eyi ti ba ni pẹlu a tun maa pese àye silẹ fun eyi ti o tẹle e. A maa tun eyi ti a ti ni tẹlẹ ṣe a si maa sọ ọ di pipe. Igbagbọ́ ti wà nibẹ tẹlẹ, ṣugbọn fi iwarere kun un. Ninu iwarere tabi iwa titayọ Onigbagbọ́ ni igboya lati ṣe ati lati jiya wà. Fi imọ Ọlọrun kún iwarere otitọ, ẹmi iṣẹ ṣiṣe ati ọgbọ́n lati fi lò wọ́n. Ninu imọ rẹ ní airekọja, ipá lati fara dà ati lati dariji; lati gbeniro ati lati yẹra fun ibi. Sẹ́ ara rẹ ki o si gbé agbelebu rẹ lojoojumọ. Airekọja Onigbagbọ́ ni lati yà kuro ninu afẹ́ ẹ̀ṣẹ ti o le mu ni ṣina kuro lọdọ Ọlọrun. Eyi ni lati lo ayé bi o ti yẹ. Lati rekọja jasi ṣiṣi anfaani yii lo (Ka 2 Kọrinti 10:5). Ki airekọja ati iko-ara-ẹni-nijanu má ba le koko ju, ki o nira tabi rorò ju, a gba wa niyanju lati ni suuru. "Ninu sũru nyin li ẹnyin o jère ọkàn yin" (Luku 21:19). A ni lati fi iwa-bi-Ọlọrun kún suuru, mimọ̀ nigba gbogbo pe a wà niwaju Ọlọrun ati gbigbẹkẹle E. A ni lati fi ifẹ ọmọnikeji kún iwa-bi-Ọlọrun eyi ti yoo maa wá ire ọmọnikeji wa. Ọlọrun n fẹ ki a ni ifẹ ti yoo tayọ ọdọ arakunrin wa si aladugbo wa; nipa bẹẹ,

gęgę bi afikun ti o kó akopọ gbogbo rẹ̀, a fi ifẹni kun un.  Ifẹ Ọlọrun yii ninu ọkàn wa a maa wò rekọja a si gbá gbogbo ẹda mọra pẹlu (1 Kọrinti 13).

Bi awọn oore-ọfẹ wọnyii ba wà ninu wa, ki i ṣe kiki pe ki o wà nibẹ lasan ṣugbọn ki wọn maa dagba ki wọn si maa pọ si i, a ki yoo fà sẹyin ninu iṣẹ tabi ki a jẹ́ onilọra, ṣugbọn a o maa so eso fun Ọga wa. Ẹni ti o ba kuna ninu awọn oore-ọfẹ wọnyii jẹ́ afọju.  Oju imoye rẹ̀ ti fọ́.  Kò le ri Ọlọrun tabi ifẹ Rẹ̀ ti n dariji ni.  O ti sọ idaniloju ohun ti a kò ri nù.  Oju ẹmi rẹ̀ kuru, nitori ko ri awọn ileri iyebiye wọnni, ifẹ pipé, ati Ọrun.  Nisisiyii ko tun ri awọn ohun wọnni ti o ti n gbadun tẹlẹ ri mọ́, o si ti gbagbe iriri ti o ni nigba ti a dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i.

### Ipè ati Yiyàn ti o Daju

Bi o ti n ba awọn ará sọrọ, Apọsteli ni gba ni niyanju pe ki a maa ṣe aapọn lai sinmi lati gbọran si ipe ti Ọlọrun pe wa si, igbagbọ́ ati iwa mimọ́, ati yiyàn si ipo kan laaarin Israẹli nipa ti ẹmi.  Bi a ba tẹramọ ati maa ṣe ohun wọnni ti awọn ẹsẹ ti o ṣaaju nì wi pe ki a ṣe, Ọlọrun fun wa ni idaniloju pe a ki yoo ṣubu.  Eyi n kọ́ wa pe a o ṣubu bi a ko ba ṣe nnkan wọnyii.  Ẹni ti o gbọran ni a o pese fún lọpọlọpọ lati wọ ijọba Ọrun.  Gẹgẹ bi oloootọ oluṣọ-agutan,  Peteru ṣeleri lati maa rán awọn ijọ rẹ̀ leti nnkan wọnyii, ki a ba le fi ẹsẹ̀ wọn mulẹ ninu otitọ.

### Ori Oke Ipalarada

Peteru mọ pe iṣẹ-iranṣẹ oun laye n lọ si opin, pe oun ki yoo le maa waasu ki oun si tun maa kọ́ ni.  O n tẹ ẹ mọ wọn leti bi o ti ṣe pataki lọpọlọpọ to lati tẹle awọn ẹkọ Kristi ti oun ti gbọ́ ni ẹnu Olukọni naa tikara Rẹ̀.  Akọsilẹ yii mu ki ohun ti o ṣẹlẹ lori Oke Ipalarada ki o yé wa ju bẹẹ lọ ati bi awọn iṣẹlẹ wọnni ti fi idi awọn asọtẹlẹ Majẹmu Laelae mulẹ.  Peteru n sọ nisisiyii bayii pe Ihinrere yii ati ọrọ yii ki i ṣe itan asan eyi ti a tipasẹ ọgbọnkọgbọn là silẹ, gẹgẹ bi ọpọlọpọ itan ti wa nigba nì nipa iwa-Ọlọrun ati awọn angẹli.  Oun jẹ ẹlẹri ọlanla Kristi lori Oke ni.  O ti gbọ́ ohùn Ọlọkrun ti wi pe, “Eyiyi li ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dun si gidigidi: ẹ mã gbọ́ tirẹ̀”.  O ti ri bi Mose, ẹni ti i ṣe aṣoju Ofin, ati Elijah ẹni ti i ṣe aṣoju awọn wolii ti rekọja ti Jesu si nikan duro nibẹ. Jesu ni Ẹni ti a ni lati ri lọjọ oni (Deuteronomi 18:15; Luku 16:16).

### Agbara Ọrọ Ọlọrun

Awọn asọtẹlẹ nipa Kristi ti ṣẹlẹ ni kinnikinni; niwọn igba ti Peteru, Jakọbu ati Johannu jẹ́ ẹlẹri ti Ipalarada, ti wọn si ti gbọ́ ohùn Ọlọrun ti n jẹri rere nipa iṣẹ Ọmọ Rẹ̀ ni ayé, eyi tubọ n fi idi awọn asọtẹlẹ ti a ko i ti i muṣẹ mulẹ, ninu eyi ti ipadabọ Kristi si ayé wà (Iṣe Apọsteli 1:11).  Awọn asọtẹlẹ wọnyii jẹ fitila ti n tan ni ibi okunkun ti o si jẹ pataki titi ilẹ yoo fi mọ́ ti “Oorun Ododo” yoo si yọ ti yoo si le okunkun lọ.  Apọsteli yii tun kilọ lẹẹkan si i nipa ewu ti yoo wà nipa fifun awọn asọtẹlẹ inu Iwe Mimọ ni itumọ ikọkọ.  Awọn ẹni ti o kọ wọ́n ki i ṣe awọn eniyan ti ara ṣá, ṣugbọn awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun ti a n dari lati ọwọ́ Ẹmi Mimọ wá.  O gbà pe ki Ẹmi kan naa ti o dari awọn eniyan mimọ́ lati sọ ọrọ wọnyii tumọ wọn.  Iwe Mimọ́ ni o n tumọ Iwe Mimọ́, ki i si i ṣe nipa ọgbọ́n eniyan (2 Timoteu 2:15).  I ba ti wu Ọlọrun to pe ki a ri awọn eniyan mimọ́ ju bẹẹ lọ lode oni, ti a ya sọtọ fun ifẹ Ọlọrun ti Ọlọrun le lò lati sọ awamaridi ọrọ̀ oore-ọfẹ Rẹ̀ lati inu Ọ̀rọ Rẹ̀!

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ohun ti Peteri Apọsteli sọ nihin pe o ṣe iyebiye?
2 Awọn iwa wo ni a sọ pupọ si i ninu ori iwe yii?
3 Bawo ni a ṣe n fi awọn nnkan ti i ṣe ti iye ati ti iwa-bi-Ọlọrun funni?
4 Ki ni ohun ti a pè wá si?
5 Nipa ki ni a ṣe wà ni alabapin ẹda Ọlọrun?
6 Ki ni awọn iwa meje naa, ti a ba fi wọn kun igbagbọ́ ti yoo pa wa mọ́ kuro ninu iṣubu?
7 Ipo wo ni ẹni ti o ṣe alai ni nnkan wọnyii wà?
8 Ere miiran wo ni o tun n duro de ẹni ti o bá ni awọn oore-ọfẹ wọnyii ni anikun?
9 Ki ni ṣe ti a ni ọ̀rọ asọtẹlẹ ti o daju ju bẹẹ lọ?
10 Ki ni ṣe ti ko si asọtẹlẹ Iwe Mimọ kan ti ni itumọ ikọkọ?